OWE YORUBA

ASOJE OBO

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJO

VOL. XII No. 662. LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 13 – FEBRUARY 19, [illegible] KỌBỌ MEJI (2d)

# Agogoro Eyo! Hu-u Haha! Moyo Fun E, Moyo Fun'ra Mi.

EKO. O ta si wa leti fẹnrẹn wipe ọkan ninu awọn ere ti nwọn ngba lero lati fi yọ nigba Ominira ilẹ Nigeria ni ere ẹyọ Adamuorisa.

Ṣugbọn ẹnu awọn agbagba ilu koiti ko nitoripe, ere ẹyọ, oku ni nwọn fi nsin. Nigbati o ba di ọjọ na, oku tani ki awọn fi ẹyọ na sin ?.

Apa kan ninu awọn agbagba sọ wipe, ki nwọn fi ẹyọ na sinku Ologbe Oloye Abisogun, Akinṣiku Eko tabi ki uwọn fi ṣe ti ominira gẹgẹbi nwọn ti ṣe ẹyọ Red Cross ti nwọn fi sinku awọn to'ku si'ogun.



Eyọ ti a nwo ninu awọran yi jẹ ọkan ninu awọn ẹyọ "Olckun yẹmi-ade." O si jẹ ọkan ninu awọn ẹyọ ti yio ṣetafo ere na fun igba ominira ilẹ wa.

"Emi aboju pa aboju wo
Aboju komọna yẹri,
Aboju bomọ lẹru bi oriṣa"
Hu-u — haba

## Eti A Gbo're O

LONDON. A gbọ wipe nṣe ni gbogbo awon enia nfi eti leko lojojumọ lati gbọ wipe Barika! ọba obinrin bi ọmọ. Awọn Gẹsi ko fẹ ki ọba wọn joko tẹtẹrẹtẹ, nwọn fẹ ki o ma jarana.

Nitorina, ọkọ rẹ Prince Phillip mu ọba na sinu mọto lọ sibi siṣe kan ni Kensington nibiti o gbe lọ ṣe idaraya diẹ. Ọpọ awọn enia ti nṣe atiyanjiyan pe, ki o to to ipari ọsẹ ọba na yio bimọ, awọn miran sọ pe o di ẹhin ọsẹ. Ọjọ Monday ti o mbọ ni awọn ọjọgbọn f'ẹnu ko si.

## AWON OLOSA F'OGUN JA ILU ENUGU

ENUGU. Eyi ako! ki olosa gboju titi, ki nwon si fi ara won je oye Akiwande, o ma se kelebo o!

Awon olosa wo o igboro ilu Enugu lo ba onile olona woya ijakadi, nwon sa li [illegible] yanu-yanna, eniti o gbo igbe onile ti o wa sibe wa gbe ija, awon ole sa ni ada, nwon si gbe keke re lo.

A tun gbo pe awon ole nwonyi tun pa obinrin adelebo kan si eti odo kan ti o wa larin Ogui Township ati Urban-area ti nwon npe ni Mirinla, eru obinrin na ni a gbo wipe

(Wo yoku lojo ewe kejo)



## IMỌRAN FUN AWỌN KANSILỌ ILU EKO.

OLOTU,

Mo bẹ awọn Igbimọ ijọba Ibilẹ ilu Eko gidigidi ṣe ki awọn bani ṣe eto nipa ibiti Mọto yio ma kero Bọọsi (Bus), fun ima oduro kero, tabi ti ero silẹ ki ẹ ba wa ṣee ki moto na ma duro ni Ita Akanni da ero silẹ tabi gba ero, nitori didurọ Bọọsi nibẹ o ṣe anfani fun awọn ero ibi iṣẹ Kingsway Stores, fun awọn ọmọ School Zumratul Islamiyya Akọni Lagos.

Kiyesi, awọn ọkọ ti o nti Surulere wa. Yaba Oshodi Ebute-Metta gbogbo awọn ti o nṣe ni U.T.C., G.B.O awọn o ni anfani lati tete ṣe ibi iṣẹ lọ sibi iṣẹ wọn, nitori ni igbati awọn Bọọsi wa lati Tatwo Olowo, o nṣe anfani fun ona mejeji, nitorina ki ẹ jọwọ da ibuso iduro Bọọsi Ita Akọnni pada.

(Wọ yoku loju ewe kejọ)

Always ask for
'DE FACTO'
the bread with the
appetising flavour

## Alase Ile Igbimo Nilu Oyinbo



Ogbeni ti a nwo ninu aworan yi ni Sir Harry Hylton Foster Q. C. M. P., ẹni ti agbẹjọro fun ijọba Gẹsi fun ọdun marun. Ati lọdun 1905, o kọwe nile ẹkọ Eton ati ni Magdalen College, o gba aye Loya lọdun 1928, Lalẹ yi ni awọn yan si ipo alaṣẹ igbimọ nla ti London.

O gbeyawo arede lọdun 1931. Ọmọ Col Clifton Brown ti o ti wa ni ipo alaṣẹ igbimọ yi ri lo gbe niyawo arede.

# Enia Dudu Gba Iyi Nilu Oyinbo



Awọn enia dudu meji ti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbeni Titus Oluṣeyẹ Ejiwumi, ti o jẹ ọkan ninu awọn Minister ilẹ Nigeria ti o nmojuto ilọsiwaju Eko ati ọkunrin kan ara ilu Lumpur nilẹ Malaya ni awọn ọlọmọge Oyinbo nwọnyi nfi ara wọn han niwaju wọn.

## ỌKA ATI ỌBẸ SU OLE KAN, O JA BỌ NINU MỌTO

EKO. Ọkunrin ole kan, ti o jẹ gbajumọ, ti o lọ ji ero itẹwe (Type-writer) ti o si tan lọ ko wọn ni aso lodọ Oyinbo Kora kan nibiti o ngbe si Yaba, ni ọwọ awọn ọlọpa tẹ, ti nwọn si mu lọ siwaju adajọ ni kotu Yaba.

Nigbati awọn ọlọpa mu ọdaran yi sinu mọto, o lero pe bi on ba jabọ silẹ, on yio sa mọ awọn ọlọpa lọwọ samọ-samọ lọ mọ iṣẹ Ọmọ ijeka se. Boya o rope, bi nwọn ti mbọ silẹ lori ere nigbati mọto ba lẹ duro jẹ ohun ti o rọrun lati ṣe fun awọn ọmọ ljeka.

Nitorina, nigbati mọto awọn ọlọpa wa lori ere, o sare, o si fo silẹ lati inu mọto. Nigbati ejọ yi kan lati wa si igbẹjọ, awọn ọlọpa so fun adajọ wipe, awọn ọlọpa mu ọdaran na sinu mọto, o si sare jabọ silẹ nigbati mọto na mbẹ lori ere, nipa bẹ o fi ara ṣese, nwọn gbe lọ sile alaisan, asẹhinwa, asẹhinbọ, ibe lo gba yọju si ọrun, ni adajọ ba pa ejọ rẹ rẹ; o si paṣẹ ki ko ẹru fun awọn elẹru, bẹni ejọ ba mupo.

E MA KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE

## OBINRIN KAN GBA ỌLỌPA LOJU

**KADUNA.** Ọmọbinrin gbajumọ kan ti awọn apeni Jumai lo gboju gbaiya ti o si gba ọlọpa kan l o j u, ni awọn ọlọpa ba ki i mọle wipe obinrin ti o gboju gbaiya lati se iru nkan yi ko ni fi ara re lo.

Awon olopa mu obinrin na lo siwaju Alikali lati se kini oro re ki o to se ohun ti o se si olopa na, nigbati ko ri oro ti o muro muwa, Alikali ni ki o lo san ponun marun tabi ki o lo si ewon osu kan.




## Ore Lo Npani, Ore Lo Si Nla Ni.

(Lati ọwọ Ẹsọ)

Nigba aiye ọba Sango nilu ọyọ, awọn Arọkin sọ fun wa wipe, nigbati o ba gunwa, ẹefi a ma jade li ẹnu re, ni eti re, ni imu re-ati abe re.

Nigbati o ba bu ramu ramu yio dabi igbati ọkọ reluwe ba ẹefi ọkọ jade gbogbo afin a kun fun ẹefi.

Nigbogbo akoko yi ko si enti o mo ọba Sango ni oriṣiriṣi eniu awọn Bafin Oyọ ti nwon lọọrẹ Sango, ti nwon si mo pe egbogi ni Sango se de he, ni Lengbe tile Aremu kinkin rẹlẹ. Timi Agbale olofin, Otekun sile mo iyan loju, gbonka ebiri otun iwefa, ọna modeke ati ọpọ wọn be.

Gbogbo awon ti a daruko nwọ nyi lo ti mo gbogbo asiri ọbaSango, awọn si mo pe eefin ti o njade lara Sango ko le seni ni jamba awon bu iyaala iyi Sango ni ọkakan nwọn si jade kuro niwaju re ni ibinu

Nigba yi ni Sango wa mo ye, gbogbo awọn ọre on lo ti gbale yi on ka, o si P...nu lati rehin gbogbo w..a

Mortgages 1st's & 2nd's also Re-Mortgages on all classes of properties.
Particulars :
E. N. FAMERICA LTD.
31 AVENUE MANSIONS,
LONDON N. W. 3.

E MA KA IWE
IROHIN
ELETI-OFE
LỌSỌSẸ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

# ELETI-OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 3, Kosoko Street, Lagos. — P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAM — "ELETI - OFE LAGOS" — Phone 23370

VOL. XII NO. 662 SATURDAY FEB 13 - FEB. 19, 1960


## JAMBA ILE, JAMBA ODE OLUWA RERE GBAWA

Awọn Yeruba ni o ma npa l'owe wipe "Ẹbẹ ni a mbe oşika ki o ba wa tun ilu rẹ şẹ". Bi a ba be oşika ti ko ba gbọ, Ọlọrun ni a fi ale l'ọwọ. Kosi ohun ti ẹba Oluwa mi kole şe, adura ni ẹbọ Imale.

Ninu oşu yi ni Ogbẹni alagbara General De Gaule sọ wipe on yio yin etu oloro on nilẹ Yaar'n Sahara, lati fi mọ bi agbara etu oloro na ti to. gbogbo awọn orilẹ ede enia dudu jake-jado aiye ni o ti nlọgun ni ohun rere wipe agbẹdọ o, ki Ogbẹni alagbara ilẹ Faranse yi şe suure, ki o tẹdọ lori idanwo etu oloro ti o le fa jamba silẹ fun awọn ilu keke ko ti o yi ilẹ Sahara ka.

Şugbọn Ogbẹni ologun General De Gaule fi ake k'ọri wipe af'ori af'ọrun on ko ni salai dan etu yi wo. Alhadji Abu Bakar Tafawa Balewa ti o jẹ Olotu ijọba ilẹ Nigeria wọkọ lọ silu Oyinbo lo fi esun sun ijọba Gẹsi wipe on ati awọn enia ilẹ Nigeria ko fi ara mọ ti etu oloro yi, bena ni awọn enia jankan-jankan miran ni ilu yi ati ilu Aganyin sọ wipe awọn lodi si iwa tiwa mi ni ogo şe, ti alagbara ilẹ Faranse 'yi nipa etu oloro rẹ yi.

Şugbọn ogagun De Gaule kọ jalẹ wipe dandan, ayipadakosi ninu ọrọ ti on, on yio yin etu oloro na ninu oşu yi ni ilẹ Yanrin Sahara kini ẹnikan ti ao şe si ọrọ yi? adura ni ẹbọ Imale, ọro na kusi ọwọ adura, owurọ, ọsan ati ni alẹ si Ọba Ọlọrun Ọba Ogo, Ọba awọn ọba Ọba arihin-r'ọhun, Obangiriji, Ẹniti o nda abo bo ẹiyẹ oju ọrun ti o nşe itọju awọn alaini, ti o mọ ohun gbogbo ti a si le şe ohun gbogbo.

Ki Oluwa Olodumare da abo rẹ bo wa ni ilu yi, ninu jamba ti amọ ati eyiti ako mọ, ki Oba rere gbawa.






## Ogbomoso Nse Nkan



Eniti awo nin aworan yi ni Oloye S.L. Akintola ti ise Premier agbegbe Iwo-orun, Ile Nigeria.

On ni agbọ wipe awọn ẹgbẹ Ogbomọsọ parapọ se ase repete kan fun ninu ile egbe ti British Council kan nigboro ilu Ibadan l o j o Alamisi 11ht osu Feb 1960, lati fi yesi fun ipo giga ti Ọlọrun gbe si.

Ẹsẹ gbogbo awon alase ati oselu agbegbe Iwo-orun ni o pe jupese sibe.


E MA KA IWE IROHIN

ELETI-OFE

LỌSỌSẸ

O KUN FUN

IROHIN ALADUN








sasun tabi ape oka, ino sę kẹ mba'ę, o si ni saru jojo enia ko si le ba nibui o njẹun.

Bi ilẹ ba ti mọ yio lọ si ile alagba rẹ kan. Enia ko sa le ji ki o ma jẹun li owuro, yio joko ti wọn titi nwọn o fi rubą, ti nwọn o se ọbẹ, nwọn o si pe e ki o wa jẹun.

O pẹ ti o ti nhuwa yi. lojo kan ti ojo nrọ, obinrin kan nse isu lori ina, beni Ajoko-ma-dide wọle tọ wọn, o si joko. Nigbana ni obinrin yi joko ti ina o mu igi kan o fi siu Konkolo o si nkọ orin bayi pe, bi o joko o joko arode, bi o rode, o rodo apala, iwọn ọnu mi lemi gbe kana.

# Okunrin Ode Ti O Fi Omo Ekun Ko Omo Re Jade

Eeyin ọkawe wa, ẹko gidigidi wa fun wa lati o rinu itan yi, papa julọ awa ọkunrin.

Ọrẹ mi, so ahan rẹ, mase yara lati ju si ilẹ.

Nitori pe ahon re ni kinlan re, bi o ba ju silẹ yio gbeo je

Senlan ti agba fi je ẹkọ wa ni abọ ọ̀se, gbogbo wa sa ni a ni nkan ti a fi nso agbara ko ye ki a ma tu asiri nkan bayi fun obinrin wa, papa julọ obinrin ti a f e n i aitọro lowo iya ati baba.

O di ọwọ rẹ papo nibi ife ku fe, bi obinrin ba dara ti o si wun o, roju kio mo obi re ati idile re kio to fe.

Awon mejeji fi ọjo si idide won, nigbati ojo na pe, awọn dagbere fun awon ara ile o dabo! o dabo! olorun kio je ki a fi ire pade.

Bayi ni oko ati aya se lo si ona ajo awon mereji si nda ore so bi nwon ti nlo nina irin ajo nwon.

Owe Yoruba so wipe Bi ojo ba buru, ona ti o gba ologini gba omo kunrin'.

Dau daju, otito ni owe yi je fun ologbon. nwon rin titi won de lyana kan obinrin da hun pe ki awon gba ona bayi' nitoripe yio ya kia-kia si ile nwon.

Nigbati nwon de Aginju yi Iyawo dero, o ju iborun re si ile, kamari o bo buba ati gele rẹ.

Ọkọ re bere pe se k o s i nkan? oni ko si nkan.

(Koiti Pari)

# Itan Anobi Liasu

## (APA 6)

Lẹhin ti Liasu ti wọ igbẹ lọ fun ogoji ọdun, o bere lọdọ Ọlọrun, kini ẹsẹ ti on sẹ ti o mu iru ijiya yi to si on, Ọlọrun si fi ye wipe, adura Jasi-bali lo gba le lori, bi on na ba si bẹ on nise bakanna ni on yio jisẹ.

Anọbi Liasu wa toro wipe, lilọ ti on nlọ yi, nilu Jerusalem ni on nlọ, on fẹ wipe ki Jasi bali subu lulẹ lati ori afin rẹ ki o si fọ yan kan-yan kan si oju ode gbangba ki awọn aja si la oku rẹ. Ọlọrun si dahun pe on gba bẹ fun u.

Lakoko na, ni iyanmu nilu Jerusalem, ti awọn enia si bere si wa Anọbi Liasu ki o wa ba wọn bẹ Ọlọrun rẹ lati fun wọn ni onjẹ, ṣugbọn nwọn ko ri. Nibiti ọkunrin kan gbe nrin kakiri igbẹ, lo pade Anọbi Liasu.

Anọbi Liasu bere lowo rẹ kini ilu ti ri, ọkunrin na si rohin pe, lati iwon odun mẹta ni iyan ti mu ni ilu, Anọbi Liasu wi fun pe, pada nisisiyi lo si igboro Jerusalem, wifun won pe, bi o ba di ni lwoyi ọtunla, nwon o ra panu iyefun kan ni kobo kan.

Iyoku di ose ti o mbo

# AWỌN ỌLỌṢA PA AṢỌDE KAN LỌNA ṢOMOLU

ṢOMOLU. A gbọ irohin wipe, ọkunrin Aṣọde kan ti nwọn npe ni Lamidi Bello di awati ki nwọn to wa lọ iru oku rẹ jade nibiti nwọn gbe sin i si ni abule Cappa nitosi ilu Ṣomolu, lọna Ikorodu.

Nwọn sọ pe, ibiṣẹ ni Aṣọde na lọ gẹgẹbi iṣẹ rẹ, ti nwọn ko si ri ki o tun pada mọ. Awọn ọlọpa fura si iru ọna ti iku gba fi pa ọkunrin na, o le jẹ wipe awọn ọlọṣa lo pa Aṣọde na nitori ki nwọn ba le ri aye lọ ile kan ni agbegbe ibiti aṣọde na wa, ti nwọn si lọ bo mọlẹ ki ọrọ na to di mimọ.

Ọrọ na si ru awọn ọlọpa loju nwọn nse itọsẹ ọrọ na iọwọ.

# Olotu Ijoba Be Ilu Ibadan Wo

Lojo Alaruba (Wednesday) ni Olotu Ijọba Apapọ bẹ ile ere nla kan ti nwọn nkọ silu Ibadan wo. Ile ere nla na ni nwọn npe ni National Stadium, nwọn



si fi awọn igbimo ile ere na han Olotu Ijoba.

# ITAN AJOKO MA-DIDE

Lati ọwọ Akinson

Ọkunrin kan wa nilu Abẹokuta ti nwọn npe ni Akerele. ise agbẹ ni iṣẹ rẹ ṣugbọn ko ni koko

# Itan Bi Hausa Ti Se De Ariwa

Ẹni'ti o se Hausa jẹ ọkunrin alagbara kan ti o ti ile Baghdad wa, orukọ rẹ a si ma jẹ Bayajida.

Bayajida yi je Musulumi a si ma gbe ogun ọsin rẹ lọ ba awọn keferi kakiri. Nigba kan o gbe ogun ti ilu kan ti a npe ni Zidima, o si ko wọn ni ikogun.

Lẹhin igbati o segun tan o pin kiri fun ara rẹ o si pin iyoku larin awọn ọgagun rẹ. Eyiti on ko jẹ apa Iwọ-orun ilẹ na o si jẹ si Borun.

Ki a to lọ si iwaju, ao se alaye fun yin nipa Borun Borun ki nse ilẹ Hausa rara ao sọ die nipa wọn nigbamiran gẹgẹbi awọn tiṣe se ati gẹgẹbi awọn ti se dikan na pọ pẹlu Hausa.

Bayajida ko gbogbo awọn ọmọ ogun rẹ dani lọ silẹ Borun, awọn ọmọ ogun rẹ pọ awọn si ni agbara ju ọmọ ogun Borun lọ.

Bayi ti Bayajida ati awọn enia rẹ wa ni apa Iwọ-orun ti ilu Borun. Nigbati o se awọn ọgagun rẹ tan ni pe, o lọ ki awọn gbe ogun ti Borun ki awọn pa oba rẹ ki awọn si gba ijoba wọn.

Ete yi ta si awọn ara Borun leti, awọn si lọ fun oba won gẹgẹbi ohun ti nwọn gbọ. Nwọn gba oba na ni imọran pe ki o fa okan diẹ ninu awọn ọmọbinrin rẹ fun Bayajida lati fi se aya.

Oba ile Borun gba imọran awọn enia rẹ o si fa ọmọ rẹ ... ti ... fun Bayajida lati fi se aya. Bayi ni afi ọmo da ore larin Bayajida ati Oba Borun ti a ko fi ja ilu na l'ogun mọ.

(Wo yoku loju ewe keje)


# Kere o !

A ti ni orisirisi egbogi fun arun inarun ati arun Jẹdi-jẹdi. (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, l'ọkunrin ati l'obinrin, ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos



# The Nigerian Medicine Stores

"GBỌMỌRỌ"

EGBOGI ATATA FUN IGBONA OMODE, IBA ORERE, INU-IWO ATI AIPERI.



IGBONA ATI ORIṢIRIṢI ARUN MIRAN TI O MA NYỌ OMODE LENU NIGBA EHIN HIHU.

"GBỌMỌRỌ"

Dara papọ fun ọmọ Ikoko tabi Tunfulu. Kosemani ni egbogi yi fun enyin abiyamọ. Ajẹbidan ni i orukọ rẹ njẹ. Ko ni fa Jẹdijẹdi tabi igbẹ-ọrin fun ọmọde, tete wa ra tirẹ ni ṣọbu wa :

THE NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU SQUARE, LAGOS

Tabi ni awọn Ẹka wa ni :-

Port Harcourt, Jos, ati Ibadan.


## Alhaji Ribadu Di Alaga Banki



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Alhaji Muhamadu Ribadu ti o jẹ Minister fun ilu Eko, on ni a tun gbo wipe, nwon tun fi se Alaga ile ifowopamosi kan (Bank) ti o mbe nile Hausa. Awon enia meje miran tun pelu re nse igbimo Banki na. sugbon a gbo pe o ko aye na sile.

## ILE ẸKỌ GIGA BẸRẸ NI ILỌRIN

ILORIN. Awọn Olotu Ijọ Anglikan si ile ẹkọ kan si Esie ni agbegbe ilẹ Ilọrin, ti nwọn npe ni Esie Grammar School, eyi ni jẹ ile ẹkọ giga ti nwọn kọ fun anfani ati ilọsiwaju ẹkọ ni agbegbe ilẹ Ilọrin.

Bishop Oyebọde gba awọn oba ati awọn ara Ilọrin ni iyanju wipe, ohun ti o dara ni ẹkọ nipa iwe. Bi ẹkọ iwe ti niyi to bakanna ni ẹkọ nipa kewu.

E sakiyesi awọn ara ilu Eko, bi nwọn ti nran omo won lo sile kewu, beni nwọn npada ran won lo sile iwe, eyi ni asiri ti awọn ara Eko fi mọ kewu ti nwon si tun fi mọ iwe.

Alufa Adekọla so wipe nigbati ile ẹkọ na ba bẹrẹ, on ni yio se ile ẹko giga keji iru eyiti o mbẹ ni ilu Oro. Ẹgba a marun ni iye owo ti nwọn o fi parí rẹ, yio tobi, yio si gbaye jeje.




AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.

# Ijebu-Ode Railway Out-Agency

In order to facilitates the receipt despatch of traffic a railway Out-Agency has been open at Ijebu-Ode.

Freight traffic will be accepted at the Railway Out-Agency for despatch to any Station on the Nigeria Railway; and similarly traffic may be sent from any railway station in Nigeria to the Ijebu-Ode out-Agency for delivery".

HOURS OF SERVICE ARE

| | |
|---|---|
| MONDAYS — FRIDAYS | 07.00 Hrs to 12.00 Hrs |
| | — — 14.00 Hrs to 16.00 Hrs |
| SATURDAYS | — — 07.00 Hrs to 12.00 Hrs |

and at other times by special request.

The freight rates are the same as those in operation to and from Ibadan station plus 20/ per ton the cartage between Ibadan and Ijebu—Ode.

EXAMPLES OF THESE RATES ARE :

| COMMODITY | TO OR FROM | Inclusive rate per ton from or to Ijebu-Ode Out-Agency |
|---|---|---|
| GARI | Kano | 93s |
| ,, | Ilorin | 34s |
| ,, | Minna | 65s |
| ,, | Gusau | 95s |
| KOLANUT | Gusau | 182s |
| ,, | Kano | 180s |
| ,, | Malam Maduri | 190s |
| ,, | Sokoto | 201s |
| PALM OIL | Kano | 164s |
| ,, | Zaria | 155s |
| ,, | Ilorin | 75s |
| ,, | Jebba | 99s |
| SHEA BUTTER | Minna | 115s |
| ,, | Badeggi | 123s |
| BEANS | Kano | 91s |
| RICE | Gusau | 92s |
| RICE | Zaria | 84s |
| DRIED MEAT | Nguru | 145s |
| ,, | Kano | 133s |

Enquiries are invited concerning this Out-Agency, and the facilities available :

PHONE 44399 or write to :-

**District Supedentendent**
Nigeria Railway [illegible]ration
Ebute Metta [illegible]

# IYA AJE NKA

Ni owuro ọjọ alaruba, ni gbangba teju Ẹlegbata, iya ajẹ kan bere si ko ti [illegible] pa a ati awon ti o ti fi se ni ika. Nigbati iya bọ si ọwọ awọn ọmọ [illegible] nso ogulutu lu' bo ni omiran si nda yanrin lu. Ninu awon enia ti o na kan [illegible] iya na, o si da pada si inu ile wọn, ṣugbọn ohun ti o nri iya kakiri ko ju silẹ, pada jaṣa pada jade si ita.

## ỌJỌ NA PE LỌJỌ ATALATA

Bi o ti wu ki o pe to, ogorun odun mbo wa ku ọla ti [illegible] ti wipe Faranse fe yinbon etu oloro, ko yin etu oloro, eyiti gbye da aiye da si, ti Faranse taku pe ko si ẹniti o le ba sọ ọ, dandan a yafi bi awọn ba yinb[illegible] as.

Eyiti Faranse ba ma ṣe ki nwon see ọjọ Atalata 9th oṣu Feb 1960 ni ibon [illegible]yiugbon [illegible]yegede Faranse ti o ba pawa taa ti ko si le ji wa kini kẹtẹ kete lara Keteketa,

## Okunrin Ode Ti O Fi Omo Ekun Ko Omo Re Jade

Bayi ni iyawo parada kia, o di ekun o yo ẹkanna re, o si fi ehin re jade lati b a ọkunrin yi ja.

Lesekese, o ri bi okunrin yi ekun yi ati ogbọju-Ode na fi ija pẹta sina agiuju igbo,

Nigbati ogboju-Ode yi ri i pe oran na ko se mọ, o bere si wa ona lati bo o di ọkiti, ekun ko lu ọkiti o hu ọkiti je o run ọkiti womu womu.

Okunrin yi pada o di o kuta.

Gbogbo okuta to wa nibe ni ekun yi bere si ifotutu

Ode yi di omi, Eyi ni chun ti iya ekunio re ko jeki o pe ja'sa ni ojo ti o jeun yo tan, ti o ntu sori agbara re fun iyawo re titun.

Ekun yi wa rabu oro ti aya okunrin Ode yi kemo lenu ni ijo kini, o wa nsare kakiri, o npe 'Iro, Iro, Iro!, ṣugbọn ko le pe ja le.

Nitoripe ko mo ohun ti iro daro fun.

Eyi yi ni ona ti okunrin Ode yi gba bo lowo ekun yi.

Eyin okawe, o ye ki enia ko lati ko aboa re ni ijanu, ki ise gbogbo nkan ti enia mo ati ohun gbogbo ti o ri ni o le ma so jade l'enu.

Awon baba wa ama pi owe pe 'Bi oju bari enu a dake.'

Lona keji, ti a ba nbu iwa kan ti awon ara ile wa ti o feran wa ba kilo fun wa pe ki a mu owo kuro nibe o ye ki a re daradara kia ma ko si won l'enu.

Ti inu mi ni ngo se, ko si eniti iba mi so. Nigba pupọ ni o nmu oplopo ọdọ ti ode oni lọ si orun osan gangan.

Eyi ni ipari itan wa.


HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayer Kavachas, [illegible] Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 6/- Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England

## Olorun Maje Ki ekeru Kuro Nidi Eru Re

Omo erukan yi di iyawo omo oba, o di ile, won fa lo si ile oba fun omo re, awon si fun omo yi ni iyara kan.

Ni ojo keji, ni owuro kutukutu, omo yi jade lati wo ehinkule beni o ri opolo ljoun ninu ogba, awon kira won omo na si dupe fun u.

Opolo na so fun wipe ti o ba di oru, on yio ko eru re wa fun u.

Nigbati opolo pada si ile, o pe awon yoku re pe, on fe ki onikaluku da eru wa fun omo obinrin okan awon kaluku si ma tire wa.

Oganjo gan, opolo gbera, o lo si ile oko omo yi.

O po ibusun wura, fadaka, bebe ati oni wio dudu jade fun u, o tun po opolopo ohun eso fun omobinrin yi.

O se ikilo fun pe, kio mase sun lori ibusun oni irin dudu ni, ayafi ti ibinu ba fi owo kon oi ni eni.

Gegebi asa ile na, opolo so fun pe ti awon iyale re ba wa ki o Fowuro kio ma fun won ni igba obi mewa mewa, ti awon erubirin ba wa ki o, fun won ni igba obi marun-marun.

Ti awon obinrin ile ba wa bere onje, ki o ma fun won ni epo iresi kokan,

Bayi ni omo na bere si se ni ile oko re, awon si feran re gidigidi.

Eeyin okawe yi, daju—daju e mo pe 'Iununibini ki ise ai mo iwa hu.

Omo yi nse daradara pelu oko re ati awon emewa oko re.

Ao si efi pa ... Yoke yi ni wipe, iyale baraku fi nse orogun iya omo obinrin yi ko ti dehin lehin re.

---

## AWON OLOSA FO ILE ERO TELEVISION NI IKEJA

IKEJA. Irohin ta siwa leti wipe awon olosa lo fo ile ero Television ti o mbe ni abule kan ti awon ore si lbafon ni agbegbe le e/a, opo lopo nyan ti awon fi nse ero ... won ko lo, nwon si lo fi ... fun awon olopa.

Nigbati awon olopa gbo irohin yi, nwon wa ... ni oja ... moto Hilman. Ni gbati awon de ibe, bew awon ... moto Hillman kan ti ... ngangan bo wa, awon olopa ... owo fun wipe ki o duro, sugbon kaka ki o duro nse lo tunbo gbon ere si.

Ere na wa di ere Ologbo ati ekute. Awon olopa ko sinu moto nwon, nwon si bere si lepa moto ti o ko lati duro na lo. Nigbati moto Hillman na sa kiyesi pe, awon olopa nlepa on bo o tunbo gbon ere si,

Nigbati nwon le ara won bi iwon buso meji ti moto Hillman na sakiyesi pe, awon olopa fe ba on o ya si koro ibikan, ki awon olopa to de awon enia nu re ti salo Awon olopa ri die ninu ero Television ti o sonu ni Ikeja ko ninu moto na. Sugbon owo te marun ninu awon losa na.

---

## AWON OBINRIN ILU OFFA KO OJA SILE

OFFA. Awon obinrin ti o nta oja ninu oja ti Ijoba fi egbaa metala poun ko si igboro ilu Offa pinnu nwon si sopanpa lati binu fi oja sile ti enikeni ko si ni taja, lati fi han wipe ilu si nfe Woraola Isioye ni oba a t i p e n w o n k o gba Mustafa Keji ni oba rara.

Ilu ko sinmi ijakadi, ti nwon nro gingiri nitori oba titun ti nwon je fun won pelu telasi na, a si gbo wipe orin owe orisirisi ni awon enia nko lati fi han wipe awon ko ni inu didun si oba Isioye ti nwon fi agbara le jade kuro nile Ilorin.

Agbo wipe ko si ifaiya bale nigboro ilu Offa, oni ijakadi ola Kogbo, ojojumo ni nde koyede nsele lerin awon omo lehin Mustafa Keji ati awon omo lehin Woraola Isioye.

---

## AWON OLOSA FOGUN JA ILU ENUGU

(O bere loju ewe kini)

awon olosa na ko ti ko lo sugbon nwon pa obinrin u a danu lasan ni,

Awon olopa se ikede nipa awon na olosa wipe enikeni ti o ba mo nipa won ki nwon wa a rohin fun olopa.

---

## Alaiyeluwa Oba Eko



Alaiyeluwa Oba Adeniji Adele Keji, ti ilu Eko ti a nwo ninu aworan re yi ni alase ere eyo Adamu-Orisa ti o a gbo wipe nwon yio fi se eye kun ayo Ominira le Nigeria tina yi

---

## IMORA FUN AWON KANSILO ILU EKO

(O bere loju ewe keji)

Akiyesi keji ti mo fun fe toka si nipe awon Moto nwonyi omiran ninu nwon nlo to iseju marun ki o to kuro ni ibuso kan beni omiran nlo fun be lo. Nitorina, a fe ki e bi wa ye eto ti awon o ma fi yara kuro ni ibuso kokan ju bi o ti wa sisiyi lo. Eyi ... si je anfani fun awon ... ise ki awon to de ibi ise laro tabi nigbati awon ba ndari losan.

A be nyin ki e je eto dogbadogba ki a ma fi ri iru eyi mo tobe awon moto miran ti nwon ko ni isosi Iseju medogun (15 minutes) nwon koiti ni si ni ibudo, won.

Mo dupe fun aye ti Olotu gba mi.

Emi ni

Onitara

---

# POLOWO
# OJA RE SINU
# IWE
# ELETI-OFE

---


**ARA-O-LIN - IPARA ATATA**




ARA-O-LIN je ipara ti o gbamuse. O tayo gbogbo irufe egbogi bee ti o ba Fuja. O dara fun lakuregbe, egbodidun, aranlatanlatan, ehin-didun, inarada-dise, arinka-inu-egun ... apa tabi ese ro, ehori, tulu, otutu-aiya, otutu-agbari, ikun-didinu, orun-didun ati orisirisi aisan kungekunge bawonni. Nitori werewere ti o nta, awon Yoruba npe e ni "ATA", Ibo npe e ni "OSE" Hausa si npe e ni "BOROKONU". Dan igo kan wo ni 2s. 6d. (ejio Fowo-eko) lati mo bi o ti ri.Kosemani ni.

**The Egba Trading Aradan Stores,**
16 Denton Bridge St., P. O. Box 1, Ebute-Metta.


Printed & Published By The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 467 Lagos Phone 23370